# “Ẹni ti o ba gbagbe irun kan ki o yaa ki i nigba ti o ba ranti rẹ, ko si ìpèṣèrẹ́ fun un afi ìyẹn

Lati ọdọ Anas ọmọ Maalik- ki Ọlọhun yọnu si i- lati ọdọ Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- o sọ pe: “Ẹni ti o ba gbagbe irun kan ki o yaa ki i nigba ti o ba ranti rẹ, ko si ìpèṣèrẹ́ fun un afi ìyẹn: (Kí o sì kírun fún ìrántí Mi.) (Ta-Ha: 14)”.
[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ṣàlàyé pe dajudaju ẹni ti o ba gbagbe lati ki eyikeyii irun kan ti a ṣe e ni ọran-anyan titi asiko fi lọ, o jẹ dandan fun un lati tete ki o si yara lọ san an ni kete ti o ba ti ranti rẹ, ko si ìpèṣèrẹ́ ati bibo fun ẹṣẹ gbigbe e ju silẹ afi ki Musulumi naa ki i nigba ti o ba ranti rẹ, Ọlọhun sọ ninu iwe Rẹ Alapọn-ọnle pé: (Kí o sì kírun fún ìrántí Mi.) (Ta-Ha: 14), o n túmọ̀ si pe: Ki o si ki irun ti a gbagbe nigba ti o ba ti ranti rẹ.



النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee